**OWE**

Oju ni a nmo aisepo, enu ni a nmo aisiyo, obe ti ko ni eran iduro ni amo.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJO

**Asoje**

Igbalaiye, aiye ko l'eyole. B'ele loni o le ro lola.

VOL. XIV No 811 LAGOS. SATURDAY JANUARY 6, – JANUARY 12, 1962. KOBỌ MEJI (2D


# ENMO PAGIDARI ! OLE JA ALAISAN NINU ILE IWOSAN IJOBA.

ONISTHA - Agbayanu irohin ti o te si wa leti lati Onisha ni wipe awọn ologbọn jamba enia wa si Iwosan ni asiko ibẹwo, nwọn si lọ fi ara wọn pamọ sinu ọgba Ile Iwosan na.

Nigbati o'di arin'ọganjọ oru awọn jandaku na jade nwọn wọle to awọn alaisan lọ pẹlu ibọn lọwọ, o wa di iku l'o fẹ tabi ki o ko owo rẹ fun wa ? awọn alaisan ti ko fẹ ku yara nko nkan ti nwọn ni dasilẹ.

Awon ogbole na ko gbogbo awọn Olutoju alaisan da sinu iyara kan, nwon tilekun mo won sibe, nwon mba ise buburu won lo larin awọn alaisan. Gbogbo owo ati eru alaisan ti nwon ri ko le ni igba ponun (£200).

## Obinrin Bimọ Merin Lekanṣoṣo

London--Obinrin ọmọ ọdun metale-logbọn kan ni o bi ọmọ mẹrin po lekanṣoṣo, ọkunrin meji ati obinrin meji ni Essex, nwọn si sọ wipe nwọn mbẹ l'alafia.

Ọkan ninu awọn oṣiṣẹ Ile Iwosan na sọ pe nwon tete bi awọn ọmọ merin na ṣaju asiko iti won. O si ku bi ọsẹ mẹfa ki nwon to to lati wa s'aiye. Nwon nfẹ itoju gidi fun bi ọjọ meji tabi mẹta si.

## GOMINA AGBA NILU OYINBO



LẸHINTI ọlọla Dok'ta Nnamdi Azikiwe je oye Gomina Gbogbogbo ati Alase Pataki ile Nigeria ni Alaiyeluwa Elizabeth Keji Ọba obinrin ilu Oyinbo fi iwe pee lati wa bẹ ilu Oyinbo wo.

Aworan ti a nwo yi ni igbati Ọlọla Gomina de ibudo ọkọ ni Euston, London, lati Liverpool ni ibere abewo ọjọ m,kanla re nilu Oyinbo. Olẹye nla Duke ti Devonshire ni o wa pade rẹ ati awon enia jankan-jankan.


**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria

HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA ILARO, BENIN-CITY, WARRI SAPELE ABA KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE
15 THROGMORTON AVENUE, E. C. 2
Manager : F. O. Tyrrell.

Telephone : London Wall 4305
Cables & Telegrams Natbaniger London

Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.

CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURGH

**Plushes, Velvet, Velveteens**
**Demask & Building Materials**
PLEASE CONSULT
**Okunowo Brothers**
63 Massey Street, (Faji Market)
LAGOS NIGERIA
The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

**E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe**
**Losose O Ku Fun Irohin Aladun**

## OKOTIE–EBOH TUN NLO SILU OYINBO.



EKO–Oloye Festus Okotie-Eboh ti ise Alase Inawo Ijoba Apapo se Nigeria yio fi ose meta lo sile Sudan, Egypt, Lebanon ati Isreali lati ojo karun osu February 1962 de ojo kokan-le-logun.

Awon enia marun ni yio ba Oloye Okotie-Eboh lo fun eto aje fun ile Nigeria. Nina won ni Akowe Banki nla (Central Bank) Malam Mai Bornu wa.

## Oyinbo To Fe Ba Enia Dudu Lopo W'ewon

PRETORIA - Nile Afrika iha Gusu ni nwon ti ju Oyinbo kan sewon osu mefa lori esun wipe o gbinyanju lati ba awon obinrin enia dudu ... lopo.

Ofin ile na ni wipe enia funfun ati enia dudu ko gbodo lopo ta bi ki nwon ma bara won se sukesuke lati oro.

Iwa ... awon enia funfun ti o wa niha Gusu ile Afrika nhu ti gbogbo ilu fi dehin kowon nyi.

# ALASE EKO NIGERIA MBA ALASE EKO ILU OYINBO JIRORO.



Alase Eko Ijoba Apapo ile Nigeria, Ogbeni Aja Nwachukwu ni o mba Sir David Eccles, Alase Eko ti ilu Oyinbo soro ninu ile ise Alase Eko nilu nla London.

Ni asiko na ni Ogbeni Nwachukwu lo se eto eko olofe ti Igbimo Ajumose (Commonwealth Scholarship) awon omo akeko ti ile Nigeria.

... SARKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, ... Faithful Reproductions of ... Gods in the Jewelleries.
Enclose ... money order for Air Mail for Catalogues and Literature.
... SARKARA, ... Montpellier Row, ... London, ... England

## Omo Nigeria To Nsise Iwe irohin Nilu Oyinbo.



Awon ti a ewo yi ... Ogbeni Fazil Ope-Oge ti o nşişe Iwe irohin ni Eko. Lẹhin ti o ti koşe ọdun kan nile ikoşe Iwe irohin ni Opopo Regent nilu Oyinbo ni o lọ w 'şe nile 'ş Iwe irohin "Evening Mail" nilu Oyinbo.

Ọgbẹni Fazil ti şişe nile ise Onirohin Ijọba tile Nigeria ki o to lọ nilu Oyinbo lati lọ ẹkọ işẹ Iwe irohin s'.


CARSON PAINTS AND VANISHES



SOLE AGENT
IKORODU TRADING COMPANY
20, & 28, Balogun Street, Lagos


## OKU'JA WOLU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE SE TI ỌJA RE YIO FI MA TA BI IŞU AKARA GBIGBONA.

**E Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe.**

## Otito Ni Olori-Iwa

Lati Ọwọ F.O. Noble

Awon ọmode mẹta nşe ọ r ẹ po nigbakugba nigbakugba ni ile ọga won, Ekini njẹ B'ejuri ẹnu ẹpamọ, Ekeji njẹ B'ejuri ẹnu "asọ" Ẹkẹta njẹ Aşorodi bi işu mẹta. Ni ọjo kan bi won ti nşerepa wọn digbolu jingi nla ti o wa ni agbala ọga wọn, jingin na yi lulẹ o fọ tutu. Odi womi nwo ọ. Ekini ti a npe ni B'ejuri ẹnu ẹpamọ damọran wipe ẹnikeni ninu wa ko gbodọ jẹwọ bi jigin na şe fo, bi ọga won tilẹ ma lu won pa, wọn ko gbọdo tu aşiri yi.

(Wo yoku leju ewe karun)

## ELETI-OFE D'ARABA

# AWON OLURANLOWO EKO FUN ILE NIGERIA

NEW YORK - Awon enia mokandin-logoji miran tun yonda ara won lati wa şe iranlowo eko fun ilę Nigeria. Nwọn mba ọko ofurufu bọ lẹhin ikilọ gidi-gidi ti Ọgbeni R. Sargent Shriver ti o je Alakoso awon akonileko na şe fun won wipe ki nwon ni ọgbọn oye ati işora nipa iwe ti nwon yio ma ko sile lati ilę enia dudu ti Iwọ-orun.

Ẹniti o kọko wa se tṣe ni Nigeria, Margery Michel More ti da ijogbon sile iwe ti o njuwe ilu na bi ilu ti ko laju ti o si bọ sowo awon ọmọ akeko ti nwon tẹ sinu iwe irohin wọn, ti o mu ọ̀ọ̀idan Michelmore na wale.

Ẹniti awon darukọ pe yio se akoniję awọn akonilękọ na ni ilę Nigeria ni Dokita Samuel Dewitt Practor, ti işe Alakoso Ile Ẹkọ Ariwa Carolina ti o je ti enia dudu.

# AWON ENIA DUDU GUN OLORI ALUFA LOBE

BLOEMFONTEIN - Enia dudu meji ni o gun Olori Alufa (Bishop) to Ijọ Anglican ti o wa ni ilu yi lọbẹ Eni-ọwọ Alufa Bill Burnett, ni ọna merin ti i ọsan gangan ni Opopo Grahamstown ni ọjọ Alaruba ọsẹ yi.

Awọn ọlọpa ni nwon gbe Alufa omo odun medin-ladọta na lo si ile Iwosan fun itọju. Olori Alufa Burnett yi jẹ ẹni akoko ti a bi ti a si ko nilę Iha Gusu (S.A.) ti o j'oye Olori Alufa o si lodi si iwa iya enia sọto pupo, o fihan bẹ nigbati o nj'oye ninu odun 1957.

# Eniti O Kunle To Gbin Ika Ori Onika Ni Ika Ihu Le

Lati ọwọ ỌLA BABSON
(O bẹrẹ ninu iwe wa ọsẹ tokọja)

Nko la idi ohun ti mo fi sọ fun oyin nisisiyi pe fun anfani ara wa ni lati ọjọ gbọrọ ni a ti ni igbagbọ pe ti a ba tẹ ofin Ọlọrun leti ara wa ni a nşe ko si eyiti o kan Ọlọrun nibẹ.

Ọlọrun ni iwọ ko gbọdọ ya erekere kan fun ara rẹ itumọ rẹ ni wipe iwọ ko gbodọ eda ti Ọlọrun şe, ki irufẹ awon eni bi awon ti nwon ngbe Orisa bi ere kan kalẹ ti nwon pe ni Ọlọrun, ni iwọn igba ti o ba ti je wipe awa fun ara wa ni fi ọwọ ara wa ti şe e, eyi fihan wipe ohun asan ni, gẹgẹbi ẹrọ Oniwa pataki kan ati pẹlu ara wa ni a nşe.

Lehinna Ọlọrun ni ki a maşe şe afojudi si baba tabi iya wa, ki ojo aiye wa le pẹ, iyen ni wipe ki ẹmi wa le gun, şugbọn ode ti a wa nisisiyi yatọ pupọ ode lamba ati ode ike.

Ọlọrun ni a ko gbodo şe panşaga, a ko gbọdọ jẹri eke si ẹnikeji wa, ati bi iru ohun ti ko dara bi ki a ma purọ mọ ara wa, ki a ma lọ akan buruku mọ ara wa lọrun, ki a ma le bo ara wa ni aşiri owo lasan nitori Ọlọrun, ki olowo ma le şiuu talika ati awon iru iwa gbogbo ba wọnni

(Wo yoku loju ewe karun)

# Awon Omo-ogun Kekeke (Boy Scouts) Ninu Aso Titun



Awọn ọmọ-ogun Kekeke (Boy Scouts) ti ilu Oyinbo ni nwọn nfi ayipada han ninu aşọ wọn ti nwọn ti nlo tele ri. Lati owọ osi: Alan Boness ninu aşọ ti ọdun 1907; John Robert Duffy ti ọdun 1910; White ninu aşọ ti ode oni; awọn yoku ni nwọn wọ şokoto gigun ti nwọn yọnda fun lilo awọn aşiwaju ninu ọmọ Ogun.

# Eniti O Kunle To Gbin Ika Ori Onika Ni Ihu Le

Lati ọwọ ỌLA BABSON

Gbogbo awọn ohun ti a ka wọnyi, mo fẹ ki ẹ da'mi lohun, fun anfani ara wa ni tabi fun anfani ara wa kọ? Bi a ba le ri ẹni da wa lohun pe fun anfani ara wa kọ ki o si fi iwe Ọlọrun kan bi Bibeli tabi Alkurani kun idahun rẹ lẹhin, inu wa yio dun pupọ a jẹ wipe tage ọrọ li a nsọ.

Ohun pataki ti a nsọrọ le lori loni gan ni iwa ika iwa jamba ti ko jẹ ohun pataki ni ọkan ẹlomiran lati ma hu, ni igbagbọ pe ti awọn ba de ọrun awọn yio jumọ ma lọ ro o, iyen ti o ba jẹ wipe awọn ẹni bẹ ni igbagbọ otito pe a o bo wa mọlẹ, a o ji wa dide a o si jihin gbogbo iṣẹ ti a ba ṣe ni igbesi aiye wa.

Ṣugbọn awa ni igbagbọ si orin waka ti awọn Imale ma nsaba nkọ ti nwọn ba nṣe iwasu wọn pe– "A ki gbin alubọsa ko hu ẹfọ, ohun ti a ba gbin ni y'o hu ara aiye." Daju-daju ohun ti a ba gbin ni yio hu lẹhin ọla.

Ṣugbọn awa nsọ loni pe "Ẹniti o kunlẹ to gbin ika ori onika ni ika ihu le"

E gbọ bi itan kekere yi ti wi, nitori bi a ba ni k a ma fa ọrọ Oluwa yọ gẹgẹbi ko ti dara lati ma hu iwa ika fun ara wa, ilẹ yio kun.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)


Irnọ ninu iṣẹ
ọwọ pataki ni nsọ
orilẹ-ede di
ọlọrọ

Awọn egbẹ onisọwo UAC ti na £204,000 fun kikọ Ile-Ekọ ijinlẹ lorisirisi kakiri ilẹ Nigeria



Ninu awọn ti U.A.C. ti kọ ti wọn si ti gba oye ninu awọn ẹkọ ijinlẹ yi li a ti yan awọn Olukọni fun awọn Ile-Ẹkọ wọnyi. O si fẹrẹ jẹpe gbogbo wọn ni ọmọ ibilẹ Nigeria.

THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED


## OTITỌ NI OLORI IWA

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Ẹkeji ti a npe ni B'ojuri ẹnu asọ wipe a san ki a jẹwọ aṣiṣe wa ki ajiya diẹ nisisiyi ju pe ki a puro lo ti yio jadi ni ọjọ miran, ki a ma ba je a-jẹ pe-le iya lọjọ ti iro na ba ja.

Ẹketa ti a npe ni Aṣoro° di bi iṣu meta dahun wiwipe aṣiri yi ṣoro ibo nigbati ohun wa ko jẹ ọkan ekini nfe k i a ṣe, ekeji tfẹ ki a jẹwo emi ko fẹ ki a puro ki a ma ba-ba oruko wa jẹ lodo ọga wa ati lọdo awọn ara adugbo wa nitori ọjọ ti irọ ba jadi, ẹnikeni ko ni gbẹkele wa mọ. Lọna meji ao dẹṣẹ si ọdo Ọlorun t i o nri wa, nisisiyi, emi ko si f e k i ajẹwo nitori inu y i o bi ọga wa to bẹ ti yio fi le nawa pa, osi le-lo-wa sita.

Ọro yi ao ọgbon kọ, o so aṣiwere kọ, tohun-tọnu ni ọga won wọle de o ba wọn nibi apero yi, lojukanna "B'oju ri ẹnu asọ" dọbalẹ O berẹ s i ọ g a re be f u n idariji o jẹwo bi j i n g i na ṣe fọ gbogbo won si ṣe bẹ gẹgẹ ọga won ronu titi ko fẹ na won ko si fẹ fi won silẹ patapata.

Nitorina opiuu lati gba idaji owo jigia n a lowo w o n. Nwon dupẹ lọwọ ọga won nwon si jade B'ojuri ẹnu aso damoran pe ki won lo ṣe igi ta ki won ba le ri owo ti a bu fun won, nwon ṣe be won si san owo na, aṣiri yi si bo dandan, won bo lowo iya nitori nwon jẹwọ ọṣẹ ti won ṣe ọga wọn.

Bọ tan ma gbero mi ni ọsọse.

# IJA EGBE KARETA DE KOTU

EKO - Awon enia mefa ni olopa mu wa siwaju adajo Kotu Yaba ni Ebute Metta lori esun meji lilu ti awon ju Robinson E e ti Salisu Jimo ti awon da egbe siwon lara nigbati awon egbe Kareta ti Lafiaji ati awon ti Camp's (Cow boy) ja n i Oporo Lewis l'Eko ni ojo keji ojo odun Keresimesi, (26th December) 1961.

Awon ti olopa ko na ni Latifu Agbabiaka, Mufutau Aremu, Bright Omoruyi, Amusa Gasper, Joseph B baturde ati Kayode Willoughby.

Oga olopa so wipe ki Kotu ma gba iduro fun won ni oripe on sile fi esun titun ti ipania kun esun won lori iku Ijola Joseph ti o wa ninu Ija na.

Kotu fi igbigbo ejo won si ojo keji-din-logun osu January, ki awon si fi won si itimole.

KEVENTIS
SUPERMARKET
and COLD STORE
We are pleased to Announce to our customers in Lagos and Ikoyi Island that we have now started a house delivery service on Tuesdays, Thursdays and Saturdays.
PLEASE PHONE YOUR ORDER TO
24... Extension 32

## Eniti O Kunle To Gbin Ika Ori Oni'ka Ni Ika Ihu Le

(O bere loju ewe karun)
Lati owo OLA BABSON

"Ni ojo kan Ogun lo te ifa lodo Orunmila, eyiti awon ebo lagido omiran so di (Orun lo mo eniti yio la) ida kan soso lo si mbe lowo Ogun ti o fi nse okunrin.

Orunmila ni o dara, ki o mu ida kan soso na wa, ti o fi mbo fun un, Orunmila si fiida na ti si koro yara ile re.

Nigbati Ogun ko ni ida mo, o wa nse jeje kiri o si bere si sere li were-were kakiri ode awon omo were ati agbalagba si nwo to o lehin awon ko tun na fun un mo nitori ida ti ko si mo.

Ni ojo ti Ogun sere bayi de odo Orisa ti on ti owo eris lehin re ni Orisa bi i lere pe kini se o t e fi nse bayi ? Ogun dahun pe airikansekan l i o ba eyi ba on nigbati Orunmila ti yan ida owo on fi rubo ti on si ti fi fun un kosi ipa kan ti on tunsle se mo Orisa ti o ti ni Orunmila sinu teletele ko Ogun pe ki o yara lo gba ida re lowo re tabi ko mo wipe ida ti o fi nse okunrin ni ndon?

(Iyoku di ose to nmbo.)

## Oluko Di Oloye

EKO - Irohin kan wa wipe Ogbeni Isola O. Bajulaiye ti ise oga Oluko nile ikose Ijoba Apapose ni Gomina Gbogbo-gbo ti gba pe ki nwon fi j'oye Eleta Odibo ilu Eko.

Lojo Alamisi (Thursday) ni nwon mu Oloye titun na lo siwaju Oba Eko ati ijoye re ni Iga Idunganran.

Ogbeni Bajulaiye, ti o ti je akowe Igbimo Sosi Eleja nilu Eko ni nwon yio fi j'oye na losan oni Satide.

## Asia Oba Titun



Asia ti a nwo aworan re yi ni eyiti nwon se ni akanse fun Alaiyeluwa Oba Obirin Elizabeth Keji ni asiko ti o wa be ilu Saro wo.

Gbogbo ibiti e ba ti ri Asia yi ni Oba wa, ibaje inu oko, ile tabi lara moto.

Printed & Published By The Union Printing & Publishing Company 24, Kosoko Street P.O. Box 467 Phone No ....